
Àṣìrò Náà
ATỌNÀ ẸMÍ KAN, ÀNJỌNNÚ ẸKÙN ÀTI ÌYÁ KAN
TÍ Ó KỌNI LÓMINÚ!
IWỌN DIDUN ỌKAN
OWEN JONES
TEKTIME

# ÀWỌN ÀKÓÓNÚ


ÀṢÌRÒ NÁÀ
OWEN JONES
Sola Agboola
ÌFISỌRÍ
ÌJÚBÀ
ÀWỌN ỌRỌ ÌṢÍTÍ
ÀWỌN ÀKÓÓNÚ
KÒ SÍ ṢÍṢE, KÒ SÍ ÀÌṢE
2 ÌMỌLÁRA TÍ Ó NPỌ SÍI
3 OLÙRÀNLỌWỌ KÉKERÉ FÚN ÌYÁ
4 ÌMÍSÍ
5 ÀWỌN ALÁDÚGBÒ
6 ÀWỌN ỌRẸ MEGAN
ẸNI TÍ A KÒ FI ÀÀYÈ GBÀ
Owen Jones
ÌṢÒRO ỌGBẸNI LEE

## *ÌFISỌRÍ*

Mo fi àtúntẹ̀ yìí sọrí aya mi, Pranom Jones, fún mímú kí ayé mi rọ̀ mí lọ́rùn bí agbára rẹ̀ ti tó, ó nṣiṣẹ́ nlá nípa rẹ̀ àti àwọn òbí mi, Colin àti Marion, fún ìtọ́dàgbà ìyanu tí wọ́n fún èmi àti àwọn arákùnrin mi .
Karma yóò fi irú rẹ̀ san á fún gbogbo wọn ní òtítọ́.

## *ÌJÚBÀ*

Sí aya mi, Pranom fún sùúrù rẹ̀ àti ọ̀rẹ́ mi Lord David Prosser fún ṣíṣe ìrànlọ́wọ́ láti ya àwòrán ẹ̀yìn ìwé náà.

## *ÀWỌN Ọ̀RỌ̀ ÌṢÍTÍ*

"Máṣe gba ohunkóhun gbọ́ nítorí pé o sá ti gbọ́ ọ,

Máṣe gba ohunkóhun gbọ nítorí pé ọ̀pọ̀ ènìyàn sá ti sọ ọ́ tàbí pé ọ̀pọ̀ ènìyàn ti fií ṣe àhesọ̀,

Máṣe gba ohunkóhun gbọ́ nítorí pé o sá ríi tí a kọ ọ́ sínú àwọn ìwé kíkà ti ẹ̀sìn rẹ̀,

Máṣe gba ounkóhun gbọ́ nítorí àwọn olùkọ́ àti àgbààgbà nìkan,

Máṣe gba àwọn ìṣẹ̀ṣe gbọ́ nítorí pé nṣe ni a sá bá wọn lọ́wọ́ àwọn ìran tí ó ti kọjá,

Ṣùgbọ́n lẹ́yìn ìfojúsílẹ̀ àti àgbéyẹ̀wò, tí ohunkóhun bá mú ọgbọ́n wá tí ó sì ṣe àtìlẹ́yìn fún ire àti ànfààní ẹnìkan àti gbogbo ènìyàn, gbà á kí o sì gbé ìgbé ayé tọ̀ ọ́."

**Gautama Buddha**

------

Ẹ̀mí Nlá, tí ohùn rẹ̀ wà lórí afẹ́fẹ́, gbọ́ mi. Jẹ́ kí ndàgbà ní okun àti ìmọ̀.

Jẹ́ kí nrí oòrùn aláwọ̀ pupa àti ti elése àlùkò tí ó nwọ̀ títí láé. Jẹ́ kí ọwọ́ mi ṣe àpọ́nlé àwọn nnkan tí o ti fún mi.

Kọ́ mi ní àwọn àṣírí tí a fi pamọ́ sí abẹ́ ewé àti òkúta kọ̀ọ̀kan, gẹ́gẹ́ bí o ti kọ́ àwọn ènìyàn láti ìgbà ìwáṣẹ̀.

Jẹ́ kí nlo okun mi, láti máṣe pọ̀ ju arákùnrin mi lọ, ṣùgbọ́n láti bá ọ̀tá mi tí ó ga jùlọ jà – èmi fúnra mi.

Jẹ́ kí nmáa wá síwájú rẹ ní gbogbo ìgbà pẹ̀lú ọwọ́ mímọ́ àti ọkàn tí kò ní àbàwọ́n, pé bí ìgbà mi lórí Ilẹ̀ Ayé ti nparẹ́ gẹ́gẹ́ bí ìgbà tí oòrùn bá wọ̀, kí Ẹ̀mí mi lè padà sí ọ̀dọ̀ rẹ láìsí ìtìjú.

(Ó dá lórí àdúrà ìbílẹ̀ **Sioux** kan)

## *ÀWỌN ÀKÓÓNÚ*

1 Kò Sí Ṣíṣe, Kò Sí Àìṣe

2 Ìmọ̀lára Tí Ó Npọ̀ Síi
3 Olùrànlọ́wọ́ Kékeré Fún Ìyá
4 Ìmísí
5 Àwọn Aládúgbò
6 Àwọn Ọ̀rẹ́ Megan
Ẹni Tí A Kò Fi Ààyè Gbà

# KÒ SÍ ṢÍṢE, KÒ SÍ ÀÌṢE

Wọ́n tún ti Megan mọ́ ibi tí wọ́n nkó èédú pamọ́ sí lẹ́ẹ̀kan síi, ó sì ti fẹ́ máa da omi lójú. Ọmọ ọdún méjìlá péré ni, kò sì yé e èrèdí tí ìyá rẹ̀ fi ṣe ohun tí ó burú bẹ́yẹn síi. Ó ti ṣẹlẹ̀ nígbà mélòó kan tẹ́lẹ̀, ṣùgbọ́n bóyá baba rẹ̀ kò mọ ohunkóhun nípa rẹ̀. Kò tíì sọ fún baba rẹ̀ rí, ó sì dá a lójú pé ìyá òun kò tíì níí sọ nnkan kan bákan náà.

Àdéhùn ìmọ̀sínú kan wà láárín òun àti ìyá rẹ̀ pé kí àwọn méjèèjì máṣe já ara wọn kulẹ̀, ṣùgbọ́n òun tún nìyí níhín, tí ó njókòó sínú ibi tí wọ́n nkó èédú pamọ́ sí, nínú ìdọ̀tí àti ekuru pẹ̀lú àwọn ẹ̀dá búburú tí a ò lè sọ tí ó nfi ojú síi lára.

Òun ò mọ̀. Òkùnkùn ṣú dudu, ó sì lo gbogbo agbára rẹ̀ láti máṣe sọkún kí ó sì bẹ ìyá rẹ̀ láti tú òun sílẹ̀. Ṣùgbọ́n ó ti gbìyànjú ìyẹn ní àwọn ìgbà míràn, ìyá rẹ̀ sì ti sọ pé kí ó ṣe àwọn nnkan tí ó nira gẹ́gẹ́ bí èrèdí tí òun lè fi dá a sílẹ̀. Àwọn ohun tí ó mọ̀ pé kò lè ṣeéṣe, bí ó ti wù kí ó gbìyànjú tó.

Nígbà míràn, ó máa ndàbí ẹni pé òun nìkan ni ó ka àdéhùn náà sí.

Omijé tún bẹ̀rẹ̀ síi fúnra rẹ̀ ṣàn lọ sí ẹ̀rẹ̀kẹ́ rẹ̀, tí ó ngbẹ́ ipa odò àìrí la ekuru ojú rẹ̀ kọjá, tí ó nṣan ekuru èédú lọ sí ìsàlẹ̀ aṣọ ẹgbẹ́jọdá ilè-ìwé rẹ̀. Ó ti pọ̀jù, ó dìídì pọ̀. Báwo ni ẹnìkan tí wọ́n jọ gbọ́ ara wọn yé dáradára tó bẹ́ẹ̀, ti lè hùwà tí ó burú bẹ́yẹn sí ọmọbìnrin rẹ̀ kanṣoṣo?

Megan kò mọ ìgbà tí ó tọ sókè bí ìyá rẹ̀ ti mọ̀ọ́mọ̀ fi ẹ̀rọ ìnulẹ̀ gbá ilẹ̀kùn nígbà tí ó nkọjá lọ. Kò tilẹ̀ sí ìmọ́lẹ̀ tí ó kéré jùlọ tí ó lè mú ìrọ̀rùn wá, nítorí náà ó ṣe ohun tí ó rí pé ó ran òun lọ́wọ́ jùlọ. Ó gun orí èédú tí wọ́n kó jọ, ó gba ibẹ̀ dé ara ògiri títí tí ó fi dé ara igun ilé.

Níbẹ̀, ó fi yẹ̀rì rẹ̀ di ẹsẹ̀ rẹ̀ kí ohunkóhun tí ó nrákò má bàá rín í lára kí ó sì lẹ̀ mọ́ ọ ní abẹ́. Ó de gbogbo bọtinì ara ẹ̀wù rẹ̀, ó fa ìbọ̀sẹ̀ rẹ̀ sókè, ó fa ẹ̀wù òtútù rẹ̀ borí rẹ̀ ó sì ki apá rẹ̀ bọnú aṣọ rẹ̀. Pẹ̀lú èyí, Megan mọ̀ pé ẹ̀mí òun dè lọ́wọ́ ohunkóhun tí ó ngbé nínú ibi tí wọ́n nkó èédú pamọ́ sí náà. Àwọn ànjọ̀nnú àti àwọn nnkan bẹ́yẹn kò yọ ọ́ lẹ́nu, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyẹn gangan ni ojúlówó ìṣòro tí ó wà níbẹ̀, ṣùgbọ́n kò fẹ́ kí àwọn kòkòrò máa rin ara òun, kò sì fẹ́ fi inú ro ìṣẹ̀lẹ̀ pé kí nnkan bu òun jẹ tàbí kí ó fa ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ mu.

Bákan náà, ó kórira àwọn alántakùn, ṣùgbọ́n bí ó ti di ara rẹ̀ sínú aṣọ ẹgbẹ́jọdá ilé-ìwé rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àpò, ó mọ̀ pé ààyè díẹ̀ ni ó wà ní awọ ara òun lókè ìbọ̀sẹ̀ òun tí àwọn kòkòrò tí ó nrìn lè dé. Kí a kúkú sọ pé ínṣì díẹ̀ ní tìbú-tòòró, nítorí pé apá rẹ̀ ti sún ẹ̀yìn itan rẹ̀ mọ́ itan rẹ̀ típẹ̀típẹ̀.

Ìbá wù ú kí ó lè ṣíwọ́ ẹkún sísun, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé fún sáà díẹ̀, ṣùgbọ́n ó mọ̀ pé lẹ́yìn-ò-rẹyìn òun yóò ṣíwọ́ bí ó ti nretí pé kí wọ́n dá òun sílẹ̀. Ó mọ ìgbà tí ìyẹn yóò jẹ́ bákan náà – ní nnkan bí aago márùn àbọ̀, èyí tí yóò fún u ní ìdajì wákàtí láti fọ ara rẹ̀ mọ́ kí baba rẹ̀ tó ti ibi iṣẹ́ dé.

Èrèdí tí ìyá Megan fi nṣe èyí yé e. Òun ni pé ẹ̀rù nbà á tí ẹ̀rù ò sì ba Megan. Ẹ̀rù nba ìyá rẹ̀ nítorí ọmọ rẹ̀ obìnrin, nítorí náà ó fẹ́ ṣẹ̀rù bà á gẹ́gẹ́ bí òun ti nbẹ̀rù. Ìṣòro tí ó wà níbẹ̀ ni pé Megan kò bẹ̀rù, kò sì rí nnkan kan láti bẹ̀rù nípa rẹ̀. Ó ti gbìyànjú láti ṣàlàyé rẹ̀ fún ìyá rẹ̀ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbà, ṣùgbọ́n nṣe ni ó sá npa á lẹ́nu mọ́ ní ọ̀nà tààra tàbí ní ọ̀nà ẹ̀rọ gẹ́gẹ́ bíi ti ìsisìyí.

Ọmọ Ìjọ Katolikì ni àwọn òbí rẹ̀ méjèèjì, ṣùgbọ́n ìyá rẹ̀ fi gbogbo ara gba ẹ̀sìn Katolikì náà tí baba rẹ̀ kò sì fi gbogbo ara gbà á. Ìgbé ayé lẹ́yìn ikú nba ìyá rẹ̀ lẹ́rù, nítorí náà ó wípé, ṣùgbọ́n kìí ṣe fún òun fúnraarẹ̀, níwọ̀n ìgbà tí ó ka ara rẹ̀ sí ọmọ Ìjọ Katolikì gidi tí ó sì dá a lójú pé ààyè òun ti wà ní Ọ̀run ná, níwọ̀n ìgbà tí ó bá ti ntẹ̀ síwájú láti máa ṣe ojúṣe rẹ̀. Ní ti Megan, ìṣòro tí ó wà níbẹ̀ ni pé ìyá rẹ̀ gbà pé ara ojúṣe òun ni láti máa ti ọmọbìnrin òun mọ́ ibi tí wọ́n nkó èédú pamọ́ sí, èyí tí ó fà á tí ó fi wà níbẹ̀ nísisìyí.

A ti bí baba rẹ̀ náà sínú Ìjọ Katolikì, ṣùgbọ́n kò fi gbogbo ara gbà á bíi ti ìyá rẹ̀. Baba rẹ̀ gbàgbọ́ pé tí àwọn ènìyàn bá fẹ́ fi ara wọn wewu ìdálẹ́bi ayérayé, a jẹ́ wípé ó kù sí ọwọ́ wọn. Ọ̀rọ̀ ti ọkàn rẹ̀ àti ti àwọn tí ó fẹ́ràn ni ó ká a lára, ṣùgbọ́n ó gbàgbọ́ díẹ̀ nínú yíyàn fúnra ẹni, fún àwọn ọmọdébìnrin kékeré pàápàá.

Megan nífẹ̀ẹ́ àwọn òbí rẹ̀ méjèèjì láìfi ti ohun tí ìyá rẹ̀ ṣe síi ṣe, nítorí pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ ọmọdé, ó dá a mọ̀ pé ìyá òun ní ìfẹ́ tí ó dára jùlọ lọ́kàn fún òun. Ó tilẹ̀ gbìyànjú láti nífẹ̀ẹ́ àwọn méjèèjì bákan náà, ṣùgbọ́n ìṣòro tí ó wà níbẹ̀, gẹ́gẹ́ bí èrò ọkàn Megan, ni pé ìyá rẹ̀ kò ti ní olùkọ́ rere rí tàbí pé ẹ̀rù ti bà á jù láti gba ojú, etí, tàbí ìmòye rẹ̀ gbọ́.

Ohun tí wọ́n jẹ́ kò dá a lójú gidigidi, ó sá mọ̀ pé òun ní wọn. Bẹ́ẹ̀ sì ni ó rí fún àwọn ẹlòmíràn, ṣùgbọ́n pé ìyá òun ò gbà bẹ́ẹ̀. Nítorí náà, ìyá rẹ̀ ò fẹ́ gbàgbọ́ pé àwọn míràn ní ojú, etí àti ìmòye bákan náà. Ìyá rẹ̀ 'sá' ti sọ fún u pé, 'Ọmọ ọdún mẹ́rìnlélọ́gbọ̀n ni mi, ìwọ sì jẹ́ ọmọ ọdún méjìlá péré. Ilé-ìwé

Ìjọ Katolikì ni mo ti kàwé, ṣùgbọ́n ìwọ lọ sí ilé-ìwé girama tí kìí ṣe ti ìjọ kan'.

Ó hàn pé ìyá rẹ̀ ò tíì ní ìṣòro pẹ̀lú ètò ẹ̀kọ́ girama, ṣùgbọ́n nṣe ni ó ti fi ìwà-n-wara sọ ọ̀rọ̀ náà 'tí kìí ṣe ti ìjọ kan' jáde. Ìṣòro náà ò yé Megan rí. Ó ti rí ẹni ibi àti ẹni ire, ẹni tí ó já fáfá àti ẹni tí ò já fáfá; ẹni tí ó ní ìmọ̀lára àti èyí tí ò ní ìmọ̀lára láti inú gbogbo ẹ̀sìn.

Ara àwọn tí ó ní inúure, tí ó já fáfá tí ó sì ní ìmọ̀lára gidigidi ni ìyá Megan wà.

Baba rẹ̀ jẹ́ ẹni rere, ó já fáfá ó sì ní ìmọ̀lára dé ààyè kan.

Megan gbà pé òun jẹ́ ẹni rere, tí ó já fáfá díẹ̀ tí ó sì ní ìmọ̀lára púpọ̀.

Ìṣòro rẹ̀ nìyẹn. Ìdí nìyẹn tí ó fi kájọ sí igun ihò èédu kan tí ó dúdú kirikiri pẹ̀lú onírúurú àwọn nnkan tí ó nrákò ní gbogbo ara rẹ̀ ní iṣẹ́jú ààyá yìí gangan. Ìrònú náà mú u gbọ̀n, ṣùgbọ́n ẹkún sísun náà ti dópin nísisìyí gẹ́gẹ́ bí ó ti mọ̀ pé yóò dópin lẹ́yìn-ò-rẹyìn.

Ó mọ̀ pé ohun méjì ni òun lè ṣe.

Ó lè sọ ohun tí ó nyọ́ ọ ṣe fún baba rẹ̀ kí ó sì dá ìjà sílẹ̀, èyí tí ó lè yọrí sí ìkọ̀sílẹ̀ tàbí kí a mú u lọ sí ibi ìtọ́jú tàbí ó lè díbọ́n pé òun ò mọ̀, gẹ́gẹ́ bí ó ti máa ntọ́ka síi tẹ́lẹ̀.

Megan ti kọ́gbọ́n pé ohun tí ó dára jùlọ láti ṣe nígbà tí wọ́n bá ti tìí mọ́ ibi tí wọ́n nkó èédú pamọ́ sí, ni láti máa ronú nípa nnkan míràn. Àkòrí ọ̀rọ̀ tí ó sì fẹ́ràn láti máa ronú nípa rẹ̀ jùlọ ni àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀. Kò ní ọ̀rẹ́ púpọ̀ ṣùgbọ́n wọ́n ṣe pàtàkì síi. Àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ tí ó yàn láàyò ni baba rẹ̀ àgbà, Wacinhinsha pẹ̀lú ológbò rẹ̀ tí ó nsìn.

Ó di ojú rẹ̀, ó gbìyànjú láti fi ara balẹ̀ ó sì gbìyànjú láti fi ojú inú wò wọ́n tí wọ́n ndúró níwájú rẹ̀ tàbí tí wọ́n njókòó sí ẹ̀gbẹ́ rẹ̀. Gbogbo ìgbà ni èyí nmú kí ara rẹ̀ yá gágá. Nítorí náà, ó máa nṣe èyí ní gbogbo ìgbà tí inú rẹ̀ ò bá dùn. Ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọgbọ́n ẹ̀wẹ́ rẹ̀ kéékèèké láti gbé ara rẹ̀ ró nígbà tí ó bá dàbí ẹni pé nnkan ò ṣẹnuure.

Megan rò wípé òun ní ìmọ̀lára pé nnkan kan nha ara itan òun, ó sì ngbọ́ tí nnkan kan ndún lábẹ́ ẹ̀wù òtútù rẹ̀.

Fún sáà kan, Megan gan nítorí ìfòyà.

# 2 ÌMỌ̀LÁRA TÍ Ó NPỌ̀ SÍI

Gbogbo rẹ̀ ti bẹ̀rẹ̀ nígbà tí ó ṣì nrákò. Wọ́n fìí sílẹ̀ sọ́dọ̀ ìyá ìyá rẹ̀ ní ọ̀sán, nítorí pé àwọn òbí rẹ̀ méjèèjí ni ó nṣiṣẹ́. Àwọn òbí rẹ̀ àgbà jẹ́ ẹni tí ó ka ìṣẹ̀ṣe sí, èyí tí ọkọ njáde lọ ṣiṣẹ́ tí aya sì ndúró sílé tí ó sì nṣe ohunkóhun tí ó bá lè rí ṣe nínú agbo ilé níbi tí àwọn ọmọ ti ṣe ìgbéyàwó tí wọ́n sì ti

**You’ve Just Finished your Free Sample**

**Enjoyed the preview?**

**Buy: http://www.ebooks2go.com**